William Bascom, Director
Museum of Anthropology
University of California
Berkeley 4, California

William R. Bascom
Northwestern University

BASCOM

# IWE ADURA GBOGBO-NSE

TI A NPE NI

KỌKỌRỌ IWOSAN,

TABI

Lilo Awọn Psalm Jati Tọrọ

Ohun-gbogbo lọwọ Ọlọrun.

NIPA

J. F. O. BABAFẸMI,
*Evangelist, Ikoyi.*

*Printed & Published By*

THE ILARẸ PRESS,
OGUNPA ROAD,
IBADAN.

*All Rights Reserved.* 1937.

# PREFACE.

## Ọrọ Akiyesi.

Mo ṣe iwe kekere yi fun anfani awọn ti nfẹ Ọlọrun ti wọn si njijakadi lojojumọ lati mọ ọna ti wọn yio gba de ọdọ Rẹ. Ọna ti ẹnikẹni ninu ọmọ enia ti ẹmi rẹ mbẹ ni iho imu rẹ le gba de ọdọ Ọlọrun ko ju ọna adura lọ.

Ẹniti yio ba wa ohunrere lọdọ Ọlọrun ni lati fi ara rẹ fun adura gbigba ninu ayọ tabi wahala a'v... Lọ wo Episteli Jakobu ori 6 : ẹsẹ 13 ati ori 4, ẹsẹ 7-8.

Bẹni ẹnikẹni ti o ba si nfẹ ki Ọlọrun gbọ ti oun ni lati ṣe ifẹ Ọlọrun ṣaju, ni igba nā ni ipo ti Ọlọrun nfẹ fun wa bi ọmọ yio to jẹ tiwa. Lọ wo Psalm 2 ẹsẹ 2 de 7.

Njẹ ọmọ wo ni ngbọ ti (Baba) Baba rẹ ti yio bẽre ohun rere lọdọ baba nā ti ki yio fi tayọtayọ ṣe e fun u ?

Ẹni ti o ba fẹ mọ agbara ti awọn Psalm wọnyi ni ki o lo wọn gẹgẹ bi eto ati ilana rẹ, ki o si fi igbẹkẹle ti o daju gbadura. Lọ wo Jakobu 1, ẹsẹ 6 de 8, Mark 17 : ẹsẹ 22 de 24, Psalm 37 . ẹsẹ 5 de 8.

Ko si ẹniti yio mã wà mọto lọ ti yio mã wo ẹhin ti ki yio ṣubu. Bi iyemeji ba ti kuro, oluwarẹ yio ri ohun rere ti o ba bẽrè gbà li aiṣe aniani.

Ki Ọlọrun ninu anu Rẹ ma ṣai jẹ ki iwe yi ṣe gbogbo awọn ti yio ka a ni rere, ki O si mu eleyi di mimọ; ki o wo awọn agbọgbẹ sàn: ki O mu alaileso seso: ki O le mu ọkan ti eṣu ti fi ẹtàn rẹ mu, tutu di gbigbona ninu igbagbọ ododo: ki O mu alagidi tẹriba: ki O mu awọn ti o ti ṣako pada mọ titobi Iku ati Ẹjẹ Jesu lori wa. Amin.

Lakotan, ara, ẹ mã gbadura; adura li ọpa itilẹ onigbagbọ.

Ti ẹyin ninu Jesu Oluwa,

J. F. O. BABAFẸMI,

*Evangelist, Ikoyi.*